# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OSÙ KÁRÙN, ỌDÚN 2023**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

## OṢÙ KARÙN – OGUN LÒDÌ SÍ ÌDÈ OLUBI

1. **Ó ha lè jẹ́ pé mò n’pín**

Nínú ẹ̀jẹ̀ Olùgbàlà?
P’O kú fémi t’Ó dá lóró,
T’ó lépa Rẹ dójú ikú?
Ìfẹ́ ‘yanu! è há tí ṣe,
Tí ‘Wọ Ọlọ́run kú fún mi?

Ìfẹ́ ‘yanu! e há tí ṣe,
Tí ‘Wọ Ọlọ́run kú fún mi?

2. Ohun ‘ìjìnlẹ̀! Ọlọ́run kú!

Taní mọ ìdí ète Rẹ̀?
Lásán l’ángẹ́lì ta kọ́ da,
Nfẹ́ mọ, jìnlẹ̀ ìfẹ́ mímọ́!
Ànú ṣá ni! K’áyé júbà,
Kí ángẹ́lì ma wádì mọ́.

Ìfẹ́ ‘yanu! e há tí ṣe,
Tí ‘Wọ Ọlọ́run kú fún mi?

3. O f’ìtẹ́ Bàbá Rẹ̀ sílẹ̀,

Ore-ọ̀fẹ́ Rẹ kò lópin!
Ó bọ́ gbogb’ ògo Rẹ̀ sílẹ̀,
Ó kú fún ‘ran ọmọ Ádám,
Ànú ṣá ni, láìní ìwọ̀n;
L’Ó wá mi rí, Ọlọ́run mi.

Ìfẹ́ ‘yanu! è há tí ṣe,
Tí ‘Wọ Ọlọ́run kú fún mi?

4. Ó pẹ́ ta ti de ẹ̀mí mi,
Ṣinṣin l’ó kun ẹ̀wọ̀n ẹ̀ṣẹ̀;
Ojú Rẹ́ tàn ‘mọ́lẹ̀ ìyè,
Mo tají, túbú sí mọ́lẹ̀;
Ẹ̀wọ̀n mí bó, mo d’omìnira.
Mo dìde, mo sì ntọ̀ lẹ́yìn.

Ìfẹ́ ‘yanu! è há tí ṣe,
Tí ‘Wọ Ọlọ́run kú fún mi?

5. Èmi kò jáyà ẹ̀bi mọ́:
Tèmi ni Kríst, pátápátá!
Mo yè nínú Olórí mi,
A f’òdodo ọ̀run wọ̀ mí,
N’ígboyà mo súnmọ́ ìtẹ́,
Mo gba adé, lágbára Krístì.

Ìfẹ́ ‘yanu! è há tí ṣe,
Tí ‘Wọ Ọlọ́run kú fún mi?

**1. Àwọn t’ó m’Ọlọ́run, y’ó mú ọkàn le**
Nwọn ó j’alágbára lí ojú ìjà
Èyí n’ìlérí t’Ólúwa ṣe fún wa
Pe á ò ma ṣe iṣé agbára nlá wá

Ìṣẹ́gun, Ìṣẹ́gun
Ìṣẹ́gun t'a f'ẹ̀jẹ̀ rà
Ìṣẹ́gun, ìṣẹ́gun ni ojójumọ́
Jésù Balógùn wa, agbára wa k'yó yẹ̀.

2. Lárìn wàhálà nlá, máṣe sẹ́ 'gbàgbọ́
B'agbára bí aṣẹ́gun n'nú iná 'dánwò
Fi idà Ẹ̀mí rẹ ṣiṣẹ́ agbára
Fa ẹlòmíràn wá, sì yìn Olúwa

Ìṣẹ́gun, Ìṣẹ́gun
Ìṣẹ́gun t'a f'ẹ̀jẹ̀ rà
Ìṣẹ́gun, ìṣẹ́gun ni ojójumọ́
Jésù Balógùn wa, agbára wa k'yó yẹ̀.

3. Jẹ́ alágbára, sì kọjújà s'ọ́tà
Ma yan bí aṣẹ́gun n'nú iná 'dánwò
Fi idà Ẹ̀mí rẹ ṣiṣẹ́ agbára
Fa ẹlòmíràn wá, sì yìn Olúwa.

Ìṣẹ́gun, Ìṣẹ́gun
Ìṣẹ́gun t'a f'ẹ̀jẹ̀ rà
Ìṣẹ́gun, ìṣẹ́gun ni ojójumọ́
Jésù Balógùn wa, agbára wa k'yó yẹ̀.

## ỌRỌ̀ AGBÁRA

1. Gbogbo agbára tó gba iṣẹ́ ibi ṣe, láti ta ẹ̀jẹ̀ sílẹ̀ kólè pa ayànmọ́ mi run, àrá Ọlọ́run yóò ṣán pa ọ́ lónì, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo ẹyin búburú, tí wọ́n gbìn sínú ara mi láti fa ikú àìtọ́jọ́, idà iná yóò fà ọ́ tu kúrò nínú ayé mi lónì, èmi yóò gba ìtúsílẹ̀ mi, ní orúkọ Jésù.
3. Àwọn agbára tó n ṣiṣẹ́ láti gún abẹ́rẹ́ májèlé sínú àgọ́ ara mi, òní lòpin yín. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ẹ bẹ̀rẹ̀ siní mú májèlé yin, ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo ẹranko láti ìjọba omi, tó n farahàn lójú àlá mi, gbiná, kosì kú, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo àṣẹ láti àjọ àjẹ́, tí wọ́n ṣe lòdì sí ayànmọ́ mi yóò tapadà lónì, ní orúkọ Jésù.
6. Nípa ìfarahàn agbára Ọlọ́run níhìn lónì, àyànmọ́ mi yóò gba ìtúsílẹ̀ kúrò nínú ègún tímo mọ̀ àti èyí tí nkò mọ̀, ní orúkọ Jésù.
7. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí agbára àjèjì tí wọ́n yàn kó ma a tọpinpin ayé mi poora dànù lónì, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

### ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ògo mi, gbọ́ Ọ̀rọ̀ Olúwa, jáde kúrò nínú àhámọ́ ìgbèkùn ọ̀tá, ní orúkọ Jésù.
4. Agbára àjínde Jésù Krístì Olúwa, bàlé àyànmọ́ mi báyì, kí O sì túmisílẹ̀ kúrò nínú ìgbèkùn ìrandíran, ní orúkọ Jésù.

5. Gbogbo ìka àjẹ́ tó n gbógun ti ayànmọ́ mi, gbiná, ní orúkọ Jésù.
6. Ìlera mi nínú ìgbèkùn òkùnkùn, bẹ́ jáde báyì, ní orúkọ Jésù.
7. Báyì ni Olúwa wí; (dárúkọ ara rẹ), o gbọdọ̀ dìde, kí o sì tàn, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**Orin Dáfídì 62:11:** Ọlọ́run tí sọ̀rọ̀ lẹ́kàn; lẹ́rìnkejì ni mo gbọ́ èyí pé: ti Ọlọ́run li agbára.

**Orin Dáfídì 89:13:** Ìwọ ní apá agbára: agbára lí ọwọ́ Rẹ, gíga li ọwọ́ ọ̀tún Rẹ.

**Orin Dáfídì 40:13:** Kí ó wù Ọ́, Olúwa, láti gbà mí: Olúwa, yára láti ràn mí lọ́wọ́.

**Orin Dáfídì 107:20:** Ó rán ọ̀rọ̀ Rẹ̀, Ó sì mú wọn lára dá, Ó sì gbà wọ́n kúrò nínú ìparun wọn.

**Orin Dáfídì 147:3:** Ó mú àwọn onírora àyà lára dá: ó di ọ̀gbẹ́ wọn.

**Orin Dáfídì 6:2:** Olúwa, ṣànú fún mi; nítorí àìlera mi: Olúwa, mú mi lára dá; nítorí tí ara kan egungun mi.

**Orin Dáfídì 103:2-5:** Fi ibùkún fún Olúwa, ìwọ ọkàn mi, má sì ṣe gbàgbé gbogbo ore rẹ: Ẹnití ó dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì; ẹnití ó sì tán gbogbo àrùn rẹ. Ẹnití Ó ra ẹ̀mí rẹ kúrò nínú ìparun; ẹnití Ó fi ìṣeun-ìfẹ́ àti ìyọ́nú dé ọ lí adé: Ẹnití Ó fi ohun dídára tẹ́ ọ lọ́rùn: bẹ́nì ìgbà èwe rẹ di ọ̀tun bí ti idì.

**Orin Dáfídì 30:2:** Olúwa Ọlọ́run mi, èmi kígbe pè ọ́, ìwọ sì ti mú mi lára dá.

## ÀDÚRÀ LÒDÌ SÍ ÌDÈ OLUBI

1. Ayànmọ́ mi, bẹ́ jáde kúrò nínú ìdè olubi, ní orúkọ Jésù.
2. Ìwọ jẹran-jẹran àti mùjẹ̀-mùjẹ̀, pọ olubi mi, ní orúkọ Jésù.
3. Màjẹ́mù ìyówù t'ówà lárin igikígi àti olubi mi, fọ́, ní orúkọ Jésù.
4. Agbárakágbára ibi tó ti jẹ olubi mi, ní orúkọ Jésù, pọ̀ ọ́ nípa iná báyìí.
5. Ìwọ ẹ̀mí igbó, jáde kúrò nínú olubi mi, ní orúkọ Jésù.
6. Bí wọ́n bá tí lo olubi mi láti mú ìyàbàrà bá ayànmọ mí, Ọlọ́run dìde, yipadà báyìí, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ègún àjẹ́ tí wọ́n fi sórí olubi mi, fọ́ nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
8. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, tú ayànmọ́ mi sílẹ̀ kúrò lọ́wọ́ àyídáyidà olubi, ní orúkọ Jésù.
9. Ẹ̀jẹ̀ Jésù, túmisílẹ̀ kúrò lọ́wọ́ ìdè olubi, ní orúkọ Jésù.
10. Gbogbo àdàlù tí wọ́n ṣe sí ayànmọ́ mi láti inú oyún, kí ẹ̀jẹ̀ Jésù fagile, ní orúkọ Jésù.
11. Gbogbo ọfà alárìnkìrin tí wọ́n ta sínú ayé mi nípaṣẹ̀ olubi, padà sọ́dọ̀ àwọn tó rán ọ, ní orúkọ Jésù.
12. Akó ìdibàjẹ́ bá ayànmọ́, ti wọn yan lodi si ayanmọ mi nípa ṣẹ̀ olubi mi, já ìdè rẹ, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.
13. Gbogbo ọdẹ ìràwọ̀ tí wọ́n yàn tí ayànmọ́ mi nípa lílo olubi mi, já ìdè rẹ, kí o sì kú, ní orúkọ Jésù.

14. Nípa agbára tó mbẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo tú ara mi sílẹ̀ kúrò lọ́wọ́ ìdè olubi, ní orúkọ Jésù.